## ÀKÓÓNÚ


Láàngbàsà ........ iii
Àkíyèsí ........ iv

ÌTỌPINPIN ATỌ́KA ÌṢEWẸ̀KÙ AJẸMỌ́TUMỌ̀ ÀLÒPỌ̀ NÍNÚ ÀṢÀYÀN AFỌ̀ YORÙBÁ
*Òkéwándé, Olúwọlé Tẹ́wọ́gbóyè,* ........ 1-20

ÌHUN ÀTI ÌTUMỌ̀ ORÚKỌ ÀṢẸ̀DÁ YORÙBÁ NÍPA ÀFÒMỌ́ ÌBẸ̀RẸ̀
*Bísóyè Ẹlẹ́shin* ........ 21-36

ÀGBÉYẸ̀WÒ ÀKÓÓNÚ ÀTI ÌWÚLÒ EWÌ AJẸMỌ́KÙÚ LÁÀRIN ÀWỌN Ẹ̀GBÁ ÀTI ÌJẸ̀BÚ
*Kareem Múdàsírù Àbáyọ̀mí* ........ 37-54

ÌLÒ-ÒWE NÍNÚ ÀṢÀYÀN EWÌ ADÉBÁYỌ̀ FÁLẸ́TÍ
*Fátùrótì, Olúṣẹ́gun Rótìmí* ........ 55-70

ÒNKÀ YORÙBÁ ÀTIJỌ́ Ń KÚ LỌ
*Olúgbóyèga Àlàbá* ........ 71-73

ÀṢÀ ÌBÚRA NÍNÚ ÀMÚJÚTÓ ÀTI ÌYANJÚ AÁWỌ̀ LÁÀRIN ÀWỌN YORÙBÁ
*Ọlọ́fínṣao Olúkẹ́mi Morẹ́níkẹ́* ........ 74-84

NJẸ́ ÀWỌN ỌBA ṢÌ WÀ NÍ IPÒ ALÁṢẸ ÈKEJÌ ORÌṢÀ BÍ?
*Adéọlá Adíjat Fálẹ́yẹ* ........ 85-101

ÒDIWỌ̀N ÌTAYỌ BÍ FỌ̀NRÁN ÌṢỌWỌ́LÒ-ÈDÈ NÍNÚ ÌWÉ *ORIN ỌDẸ FÚN ÀṢEYẸ* TÍ ADÉBÒYÈ BABALỌLÁ KỌ
*Òkéwándé Olúwọlé Tẹ́wọ́gbóyè,* ........ 102-119

TÍTẸPẸLẸ MỌ́ ÈTÒ ỌRỌ̀-AJÉ ILẸ̀ ÒKÈÈRÈ
*Ọládélé Caleb Orímóògùnjẹ́* ........ 120-124

ÌHUN ÀWỌN ÌSỌ ẸLẸ́RÙN-ÚN *NÍ* YORÙBÁ
*Johnson Fọlọ́runṣọ ILỌRI* ........ 125 - 145



JOYTAL PRINTS: 08034237746


# LÁÀNGBÀSÀ

(Jona Ise Akada ni Ede Yoruba)


ISSN 0794 - 3881


University of Lagos



# Láàńgbàsà

© Copyright: The authors and the Department of Linguistics, African & Asian Studies, University of Lagos, Akoka – Yaba, Lagos, Nigeria **2014/2015**

All rights reserved.

ISSN: 0794 -3881

For: *The Department of Linguistics, African & Asian Studies University of Lagos Akoka – Yaba, Lagos, Nigeria.*

*Printed in Nigeria by*
**JOYTAL PRINTING PRESS**
*08034237746*



# Láàńgbàsà

**Olótùú** **Ọgbẹ́ni Dèjì Médùbí**

**Ìsọ̀ngbè Olótùú** **Ọ̀mọ̀wé Ọládiípọ̀ Ajíbóyè**

**Olùdámọ̀ràn Ìgbìmọ̀ Olótùú:**

Ọ̀jọ̀gbọ́n Gbóyéga ÀLÀBÁ
Ọ̀jọ̀gbọ́n Dọ̀tun ÒGÚNDÈJÌ
Ọ̀jọ̀gbọ́n Yẹmisí ADÉBỌ̀WÁLÉ
Ọ̀jọ̀gbọ́n Michael ABÍỌ́DÚN
Ọ̀mọ̀wé Dúrótoyè ADÉLÉKÈ
Ọ̀gbẹ́ni Diméjì AJÍKÒBI
Ọ̀mọ̀wé Ayọ̀ YUSUFF
Ọ̀mọ̀wé Délé ORÍMÓÒGÙNJẸ́
Ọ̀mọ̀wé Lérè ADÉYẸMÍ

Okewande O. T.
Dept. of Lings. & Nig. Langs.
University of Ilorin.

# Àkíyèsí

Bí o bá fẹ́ kí ọ̀rọ̀ àpilẹ̀kọ iṣẹ́ ìwádìí rẹ jáde nínú Láàńgbàsà, àwọn ọhun tí o nílàti ṣe nìwọ̀nyí:

(i) Fi àkọ̀tọ̀ èdè Yorùbá (1974) kọ ọ̀rọ̀ rẹ kí o sì fi ẹ̀dà mẹ́ta tí a tẹ̀ jáde pẹ̀lú ẹ̀dà tí a ṣe sínú CD ránṣẹ́ sí: Olótùú Láàńgbàsà, Department of Linguistics, African and Asian Studies, University of Lagos.

(ii) Lórí tákàdá A4 ni kí o tẹ̀ ẹ́ sí, kí ó má ṣe gùn ju ogún (20) ojú ìwé lọ. Fi àtò oníbejì sí ààrín ìlà kan sí èkejì.

(iii) Jẹ́ kí àwọn ìtọsẹ̀-ọ̀rọ̀ rẹ jẹyọ nísàlẹ̀ ojú ìwé tí wọ́n ti wáyé.

(iv) Kọ gbogbo àwọn ìwé ìtọ́kasí sílẹ̀ ní ṣíṣẹ̀-n-tẹ̀lé lẹ́yìn àpilẹ̀kọ rẹ.

Bí ó bá wá jẹ́ pé ìwé kan ni o fẹ́ kí a gbé yẹ̀wò nínú Láàńgbàsà, fi ìwé ọ̀hún ránṣẹ́ sí olótùú Láàńgbàsà tí àdírẹ́sì rẹ̀ wà ní (i) lókè.



# ÀKÓÓNÚ

Láàńgbàsà OJÚ ÌWÉ
Àkíyèsí iii

Láàńgbàsà OJÚ ÌWÉ

Àkíyèsí iii

ÌTỌPINPIN ATỌ́KA ÌṢEWẸ́KÚ AJẸMỌ́TUMỌ̀ ÀLÒPỌ̀ NÍNÚ ÀṢÀYÀN AFỌ̀ YORÙBÁ
*Òkéwándé, Olúwọlé Tẹ́wọ́gboyè,* ........................................1-20

ÌHUN ÀTI ÌTUMỌ̀ ORÚKỌ ÀṢẸ̀DÁ YORÙBÁ NÍPA ÀFÒMỌ́ ÌBẸ̀RẸ̀
*Bísóyè Ẹlẹ́shin* ........................................21-36

ÀGBÉYẸ̀WÒ ÀKÒÓNÚ ÀTI ÌWÚLÒ EWÌ AJẸMỌ́KÙÚ LÁÀRIN ÀWỌN ẸGBÁ ÀTI ÌJẸ̀BÚ
*Kareem Múdàsírù Àbáyọ̀mí* ........................................37-54

ÌLÒ-ÒWE NÍNÚ ÀṢÀYÀN EWÌ ADÉBÁYỌ̀ FÁLÉTÍ
*Fátùrótì, Olúṣẹ́gun Rótìmí* ........................................55-70

ÒNKÀ YORÙBÁ ÀTIJỌ́ Ń KÚ LỌ
*Olúgbóyèga Àlàbá* ........................................71-73

ÀṢÀ ÌBÚRA NÍNÚ ÀMÓJÚTÓ ÀTI ÌYANJÚ AÁWỌ̀ LÁÀRIN ÀWỌN YORÙBÁ
*Ọlọ́fínṣao Olúkẹ́mi Morẹ́nikẹ́* ........................................74-84

NJẸ́ ÀWỌN ỌBA ṢÌ WÀ NÍ IPÒ ALÁṢẸ ÈKEJÌ ORÌṢÀ BÍ?
*Adéọlá Adìjat Fálẹ́yẹ* ........................................85-101

ÒDIWỌ̀N ÌTAYỌ BÍ FỌ́NRÁN ÌSỌWỌ́LÒ-ÈDÈ NÍNÚ ÌWÉ *ORIN ỌDẸ FÚN ÀṢEYẸ* TÍ ADÉBÓYÈ BABALỌLÁ KỌ
*Òkéwándé Olúwọlé Tẹ́wọ́gboyè,* ........................................102-119

TÍTẸPẸLẸ MỌ̀ ÈTÒ Ọ̀RỌ̀-AJÉ IIỆ ÒKÈÈRÈ ....................120-124
*Ọládélé Caleb Orímóògùnjé* ....................

ÌHUN ÀWỌN ÌSỌ ELẸ́RÙN-ÚN *NÍ* YORÙBÁ .................... 125 - 145
*Johnson Fọlọrunṣọ ÌLỌRÌ* ....................



# ÌTỌPINPIN ATỌ́KA ÌṢEWẸ́KÚ AJẸMỌ́TUMỌ̀ ÀLÒPỌ̀ NÍNÚ ÀṢÀYÀN AFỌ̀ YORÙBÁ

ÒKÉWÁNDÉ, Olúwọlé Tẹ́wọ̀gboyè,
*Ẹ̀ka-Ẹ̀kọ́ Ìmọ̀-Ẹ̀dá-Èdè àti Àwọn Èdè-orílẹ̀-èdè Nàìjíríà,*
*Yunifásítì Ìlọrin, Ìlọrin.*
*E-mail Address: oluwaletewogboye@yahoo.com*

ÀṢAMỌ̀.

*Ìṣewẹ̀kú afọ̀ ní í ṣe pẹ̀lú ọ̀rọ̀-àlòpọ̀; pàápàá, pẹ̀lú ọ̀rọ̀-ìṣe àti ọ̀rọ̀-orúkọ irú afọ̀ bẹ́ẹ̀. Lílo àlòpọ̀ ọ̀rọ̀ tó ní ìsopọ̀ ìṣewẹ̀kú pẹ̀lú irú ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ ni yóò ṣàfihàn ìkógojá ìmèdè.*

*Púpọ̀ àwọn àlòpọ̀ ìtumọ̀ ajẹmọ́rọ̀-ìṣe àti ọ̀rọ̀-orúkọ ló ti di ìṣinipòpadà kúrò ní ìlànà ìṣẹ̀nbáyé (onídè); ṣùgbọ́n, tí à ń ṣe ìfirọ́pò, pàṣípààrọ̀ tàbí ìdàrọ ìtumọ̀ fún nínú afọ̀. Ìjẹyọ irú àwọn àlòpọ̀ wọ̀nyí ni a tọpinpin láti inú àwọn afọ̀ Yorùbá tó jẹ́ ọ̀rọ̀-orúkọ pọ́nbélé, ọfọ̀, àkànlò-èdè, oríkì àti òwe. Ìgbédè àti ìmèdè ní í ṣe pẹ̀lú ìṣàmúlò ìmọ̀ ìmédèlò ọ̀rọ̀ tó ní ìtumọ̀ àlòpọ̀ ìṣewẹ̀kú. Ìjẹyọ orísun ìlànà ìṣẹ̀nbáyé máa ń jẹyọ pẹ̀lú ẹranko, igi, kòkòrò, ohun abẹ̀mí àti aláìlẹ́mìí. A pín ìlànà ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-èdè fáyẹ̀wò sí mẹ́rin: atọ́ka ajẹmọ́tumọ̀ àlòpọ̀ ìṣewẹ̀kú onídè nínú afọ̀, atọ́ka ajẹmọ́tumọ̀ ìfọ́nká-aṣèyàtọ̀ àlòpọ̀ ìṣewẹ̀kú nínú afọ̀, atọ́ka ajẹmọ́tumọ̀ ìfọ́nká-aláìṣèyàtọ̀ àlòpọ̀ ìṣewẹ̀kú nínú afọ̀ àti atọ́ka ajẹmọ́tumọ̀ ìfọ́nká-aṣèyàtọ̀ àlòpọ̀ ìṣewẹ̀kú oníbàátan nínú afọ̀. A tọpinpin orísun ìjẹyọ àwọn afọ̀ tí a ṣàmúlò fún ìtúpalẹ̀ bí wọ́n ti ṣe jẹyọ pẹ̀lú ọ̀rọ̀-orúkọ tàbí àpólà orúkọ ní àlòpọ̀ pẹ̀lú ọ̀rọ̀-ìṣe láti ìṣẹ̀nbáyé nínú afọ̀: òwe, àfìwé, oríkì àti ọfọ̀. Àbájáde ìwádìí yìí fihàn pé púpọ̀ ìtumọ̀ afọ̀ tí ó ní ìṣewẹ̀kú àlòpọ̀ máa ń jẹ́ onídè; èyí tí ìtumọ̀ rẹ̀ máa ń kún, bẹ́ẹ̀ sì ni ó máa ń ní ìmọ̀lára ipa ìtumọ̀ àrà-ọ̀tọ̀. Lọ́nà mìíràn ẹ̀wẹ̀, ìpegedé ìtumọ̀ ìpele ìjẹyọ afọ̀ ìfọ́nká-aṣèyàtọ̀, ìfọ́nká-aláìṣèyàtọ̀ àti afọ̀ onítumọ̀ ìbátan dá lórí ìdọ́gba àti ìṣewẹ̀kú àlòpọ̀ ìtumọ̀ afọ̀ pẹ̀lú onídè. Àmúlò àlòpọ̀ ìṣewẹ̀kú ajẹmọ́tumọ̀ ló ń fi ìmèdè hàn nínú ìmọ̀ ìmédèlò.*

## ÌFÁÀRÀ

Púpọ̀ àwọn onímọ̀ ló ti ṣiṣẹ́ lórí ọ̀kan-ò-jọ̀kan ẹ̀yà afọ̀ Yorùbá. Olújìnmí (2012, o. i. 192-213) ṣiṣẹ́ lórí ipa tí òwe ń kó lórí ètò okoòwò àti ìṣàkóso ajẹmọ́rọ̀-ajé. Ó ṣàmúlò ọ̀kan-ò-jọ̀kan àwọn òwe ìpèníjà nídìí iṣẹ́ àṣejẹun kí ọwọ́ lè tẹ́nu. Ọmọlọ̀ṣọ̀ (2006) ṣiṣẹ́ lórí òwe bákan náà. Ó ṣàgbéyẹ̀wò ìlànà ìhun ọ̀gangan-ìpò òwe Yorùbá nínú afọ̀. Ó ní a kò lè ṣàlàyé ìtumọ̀ òwe pẹ̀lú àkóónú rẹ̀ nìkan, bí kọ̀ ṣe pé a ṣe àwòmọ́ síntáàásì ìtumọ̀ irú òwe bẹ́ẹ̀ nílànà tààrà àti ẹ̀lẹ̀lọ̀ọ̀. Ó ṣètòkasí ìpele oníbeji tí òwe máa ń gbé jáde àti ipa ààtò, ìhun àti èròjà ìmọ̀-ẹ̀dá-èdè tí ó sodo ṣínú òwe.

Ọlátúnjí (1984/2005, o. i. 169-190) pín òwe Yorùbá sí ìṣọ̀rí pẹ̀lú iṣẹ́ òwe tó ní ìpìlẹ̀ ìbáṣepọ̀ àwùjọ, ìwúlò òwe àti àwòrán-inú nínú òwe. Bámgbóṣé (1968) ṣàgbéyẹ̀wò òwe oníhun gbólóhùn abọ́dé, onìbọ̀, tẹ̀lé-ǹ-tẹ̀lé àti gbólóhùn adọ́gba. Iṣẹ́ rẹ̀ ṣíjú wa sí ìpín-sí-ìṣọ̀rí òwe Yorùbá. Nínú afọ̀ Yorùbá, òwe jẹ́ ọ̀kan lára ẹ̀yà afọ̀ tíṣẹ́ tó fẹjú jù ti wàyé.

Iṣẹ́ Àjàyí (1995) dá lé àgbéyẹ̀wò fi fi ojú ìlànà ìmọ̀-ẹ̀dá-èdè ajẹmáfọ̀ wo ọfọ̀ Yorùbá. Ó ní, ìlànà ọfọ̀ Yorùbá máa ń ní bátánì ìhun: ni, kì í, àti níí. Ó ṣàgbéyẹ̀wò ìlànà wọ̀nyí nínú ọfọ̀ ààsán, ògèdè, àyájọ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Barber (1991) ṣiṣẹ́ lórí oríkì ní ìlú Òkukù, ìpínlẹ̀ Ọ̀ṣun. Iṣẹ́ yìí jẹ́ èyí tó jinlẹ̀ lórí oríkì, orílẹ̀, ìṣẹ̀rẹ́, ipa àti ipò oríkì àti orílẹ̀ láwùjọ Yorùbá. Púpọ̀ àwọn iṣẹ́ ìṣaájú wọ̀nyí kò fi bẹ́ẹ̀ gbájúmọ́ ìtumọ̀, pàápàá pẹ̀lú ìlànà ìṣọwọ́lò-èdè, èyí tó lè ràn wá lọ́wọ́ láti lè ṣàpèjúwe ipa tí orísun ohun àfipè tó dúró fún ìtumọ̀ kó nínú afọ̀ pàápàá àwọn afọ̀ alohùn: ọfọ̀, òwe àti oríkì tíṣẹ́ ìwádìí yìí fi ṣàtẹ̀gùn àgbéyẹ̀wò.

## ÌṢEWẸ́KÚ BÍ ÌLÀNÀ ÌṢỌWỌ́LÒ-ÈDÈ

Ìṣewẹ́kú jẹ́ ọ̀kan lára òdiwọ̀n tó gbé afọ̀ ró. Ìṣewẹ́kú ní í ṣe pẹ̀lú ìbáṣepọ̀ láàárín ìkójọpọ̀, ìsopọ̀ àti ìtayọ (Awóyalé, 1989). Èyí ni bí àwọn èròjà inú afọ̀ ṣe wà ní ìbámu sí. Ojú tí a sì fi lè wo ìbámu yìí gbòòrò púpọ̀. Lójú Jakobson (1960, o. i. 358), ìṣewẹ́kú inú afọ̀ bẹ̀rẹ̀ láti orí yíyàn títí dé ìjànpọ̀. Ó ní, " the poetic function projects the principle of equivalence from the axis of selection in to the axis of combination": "àfojúdá ìlànà iṣẹ́ ewì bẹ̀rẹ̀ làti orí yíyàn tó fi dé



àlòpọ̀" Èyí fihàn pé, yíyàn ọ̀rọ̀ tó yẹ ni yóò fún afọ̀ ní ìṣewẹ́kú. Yíyàn yìí níí ṣe pẹ̀lú ìbámu tàbí ìdọ́gba ìjẹyọ àṣàyàn afọ̀ ní àyè ìjẹyọ (Okéwándé 2014).

Láìsí ìṣewẹ́kú, ìtẹ̀síwájú láàárín ìpín afọ̀ kan sí èkejì yóò pakasọ (De Beangrande àti Dressler 1981). Lawal (1997, o. i. 45) rí ìṣewẹ́kú bí àjọṣepọ̀ tó wà láàárín èrò ònkọ̀wé tàbí aṣàfọ̀ àti irúfẹ́ èdè tó lò láti gbé èrò rẹ̀ jáde. Ìpele-ǹ-pele ni èyí sì le gbà wáyé nínú afọ̀. Ìṣewẹ́kú ló ń fún afọ̀ ní ìtumọ̀. Lójú Alan àti Fabb (1990, o. i. 136),

> The central element which gives structure to discourse is that they have coherence. Some connectedness at the level of social action which holds the discourse together.
>
> Ohun pàtàkì tó fún afọ̀ ní ìhun ni ìṣewẹ́kú. Àwọn àṣọmọ́ onípele ìlànà àwùjọ tó mú afọ̀ wà papọ̀.

Ohun tó yẹ kó máa ṣe atọ́nà aṣafọ̀ ni ìlàkàkà tàbí ìgbìyànjú àmúlò àwọn àṣàyàn ìṣewẹ́kú èdè nínú ìmédèlò; yálà, nínú afọ̀ ajẹméwì, eré-oníṣe tàbí ìtàn, òwe, oríkì, ọfọ̀, àkàmlò-èdè àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ìṣewẹ́kú yìí ní í ṣe pẹ̀lú ìṣàmúlò ọ̀rọ̀ tó tọ̀nà.

Geoffery ati Short (1981, o. i. 61) ti ṣaájú wòye pé ìṣọwọ́ afọ̀ tó tọ̀nà gbọ́dọ̀ jẹ́ èyí tó ṣàmúlò ọ̀rọ̀ àlòpọ̀ tó tọ̀nà tó sì tọ súnà. Wọ́n ní:

> Good style it seems to me, consists in choosing the appropriate symbolization of the experience you wish to convey, from among a number of words whose meaning-area is roughly, but only roughly the same. That is to say, matters of style are necessary Linguistic matters.

Ìṣọwọ́ tó ní í ṣe pẹ̀lú yíyan àrokò tó tọ̀nà fún èrò ẹni nínú ọ̀kan-ò-jọ̀kan àwọn ọ̀rọ̀ tó jẹyọ pọ̀ lábẹ́ ìtumọ̀ kan náà tàbí tí ó ní ìfarapé-ìtumọ̀. Èyí ni láti sọ pé, ìṣọwọ́ afọ̀ ní í ṣe pẹ̀lú ọ̀rọ̀ Ìmọ̀-ẹ̀dá-èdè.

Èyí fìhàn pé, àlòpọ̀ ọ̀rọ̀ tó jẹ́ gbé-e-tán, tí ọ̀rọ̀ ìpàrokò dúró fún ohun àfipè láti ìṣẹ̀nbáyé (ajẹmáṣà) ni ìṣọwọ́ afọ̀ tó tọ̀nà tó sì tọ súnà jẹ́. Gẹ́gẹ́ bí èrò Alan àti Fabb (1990, o. i. 136)

> These are collocations words, since clusters of words have a particular likelihood of occurring in the same kinds of text. Words which are generally used less frequently (e.g. technical terms) have a tendency to suggest specific contexts of use than ones that are used frequently; and collocations reflect...together these signals act as markers of cohesion in a text: its property of being held together not just because of relationships between ideas or because of purposeful action behind it, but through visible connecting forms and structures in the Language itself. These markers can be of a number of types.

> Àwọn wọ̀nyí ni ọ̀rọ̀ àlòpọ̀, níwọ̀n ìgbà tí àdìpọ̀-ọ̀rọ̀ ní àyè ìyẹyọ nínú afọ̀ irú kanùn. Ọ̀rọ̀ tí kì í jẹ́ mímú lò ní gbogbo ìgbà máa ń wà fún ọ̀gangan-ipò kan pàtó...Ní àpapọ̀, àwọn àmì wọ̀nyí dúró bí atọ́ka ìṣewẹ́kú inú afọ̀: ó ní èròjà ìsopọ̀, kì ì ṣe nípasẹ̀ èrò tàbí fún ìdí kan pàtó nìkan, ṣùgbọ́n, pẹ̀lú ìsopọ̀ àfojúrí nípa ìrísí àti ìhun inú èdè. Àwọn atọ́ka wọ̀nyí máa ń jẹyọ ní oríṣiríṣi ọ̀nà

Èyí fìhàn pé, àwọn ọ̀rọ̀ àlọpọ̀ ìṣewẹ́kú kan náà máa ń jẹyọ lóòrè-kóòrè. Àwọn ohun àsopọ̀ yìí máa ń jẹ́ àfojúrí lọ́pọ̀ ìgbà; èyí ló sì máa ń ṣòdiwọ̀n ìṣewẹ́kú ní ìpele-ìpele.



## ÌFÚNNÍTUMỌ̀ BÍ ỌNÀ ÌṢAFỌ̀

Ọ̀nà mẹ́rin gbòógì ni a pín àmújáde ìtumọ̀ afọ̀ èdè fáyẹ̀wò fún ìtúpalẹ̀ sí: afọ̀ onítumọ̀ onídè, afọ̀ onítumọ̀ ìfọ́nká-aṣèyàtọ̀, afọ̀ onítumọ̀ ìfọ́nká-aláìṣèyàtọ̀ àti afọ̀ onítumọ̀ ìbátan. Afọ̀ onítumọ̀ onídè ní í ṣe pẹ̀lú afọ̀ tó ní àbùdá ìlànà ìṣẹ̀nbáyé, tí kò ṣeé yí padà. Àlòpọ̀ ìrúfẹ́ afọ̀ yìí ní í ṣe pẹ̀lú ohun ìpìlẹ̀ ajẹmáṣà; yálà, ohun tó lẹ́mìí tàbí ohun aláìlẹ́mìí. Bí àpẹẹrẹ, nínú àṣà àti ìṣe Yorùbá, bí àgbàlagbà tàbí arúgbó bá kú, wọn á ní irú ẹni bẹ́ẹ̀ kú, bí a tilẹ̀ lè da ìṣẹ̀lẹ̀ náà pè lọ́nà ẹlẹ́lọ̀ọ̀ pé irú ẹni bẹ́ẹ̀ 'fìlẹ̀ bora bí aṣọ', 'rè wálẹ̀ àsà', 'gba èkuru jẹ lọ́wọ́ ẹbọra', àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ẹ̀wẹ̀, bí ó bá ṣe ọmọdé ló kú, Yorùbá kò níí sọ pé òkú kú fún ènìyàn, bí kò ṣe pé 'ọ̀fọ̀ ṣẹ ènìyàn'. Èyí fìhàn pé, ìlànà ìṣàpèjúwe ikú ọmọdé ni 'ọ̀fọ̀', nígbà tí ikú àgbà jẹ́ 'òkú': 'òkú ẹ̀kọ'. Nínú afọ̀ onítumọ̀ ìfọ́nká-aṣèyàtọ̀, a ó rí ìjẹyọ ọ̀rọ̀ kan náà pẹ̀lú ohun àfipè ọ̀tọ̀, yàtọ̀ sí ti ìṣaájú. Irú ọ̀rọ̀ àfipè bẹ́ẹ̀ lè jẹyọ lábẹ́ ìṣẹ̀dá ọ̀wọ́ kan náà tàbí irú kanùn nínú afọ̀ ajẹmówe, oríkì tàbí ọfọ̀. Nígbà mìíràn, a ó rí ìjẹyọ ohun àfipè kan náà, ṣùgbọ́n, ní ọ̀nà ohun àfipè mìíràn nínú afọ̀. Bí àpẹẹrẹ, ohun àfipè kan náà ni 'Ewújù' àti 'Ọ̀yà' (ẹranko abirun), ṣùgbọ́n, ìjẹyọ ohun àfipè yìí máa ń yàtọ̀ lọ́pọ̀ ìgbà nínú afọ̀. Yorùbá á ní ọ̀tá ẹni kì í p'Òdù Ọ̀yà; ṣùgbọ́n, kì í jẹyọ pé ọ̀tá ẹni kì í p'Òdù Ewújù. Lọ́nà mìíràn ẹ̀wẹ̀, Yorùbá á ní, nítorí Ọ̀yà ni Ọlọ́run fi dá eèsún, kì í sì í wáyé pé nítorí Ewújù ni Ọlọ́run ṣe dá eèsún. Ìjẹyọ 'Ọ̀yà' jẹyọ bí ìfọ́nká aṣèyàtọ̀. Nínú afọ̀ onítumọ̀ ìfọ́nká-aláìṣèyàtọ̀, ohun àfipè lè jẹyọ nínú afọ̀ pẹ̀lú ohun àfirọ́pò, láì mú ìyàtọ̀ bá ìtumọ̀ afọ̀ bẹ́ẹ̀. Bí àpẹẹrẹ, omi egbò (ojú-ọgbẹ́) tó ti lómi nínú ni à ń pè ní 'ètútú' tàbí 'ọyún', èyówù ká ṣàmúlò nínú orúkọ méjèèjì yìí nínú afọ̀ kò lè fìyàtọ̀ ìtumọ̀ hàn rárá. A le sọ pé ojú ọgbẹ́ náà ti lọ́yún tàbí ní ètútú. Nínú afọ̀ ajẹmọ́tumọ̀ oníbàátan, àjọṣepọ̀ lọ́nà kan tàbí òmíràn máa ń wáyé láàrin àwọn ohun àfipè inú afọ̀. Àjọṣepọ̀ yìí lè jẹ́ ti ìbáṛẹ, bí ọ̀rẹ́, àjọgbé tàbí ti ìbátan bí ẹbí: ẹ̀gbọ́n, àbúrò, ìyá, bàbá àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bí àpẹẹrẹ, nínú afọ̀ ajẹmówe, a lè sọ pé 'ìtàkùn tó sogbá, so agbè náà ló so elégédé. Èyí ṣáfihàn ìjẹyọ ìbátan orísun kan náà láàárin 'igbá' 'agbè' àti 'elégédé'. Afọ̀ àti ohun àfipè kọ̀ọ̀kan ló ní atọ́ka àlòpọ̀ ìṣewẹ̀ẹ̀kú àdámọ́ fún ìdámọ̀; èyí tó ń kópa tó lọ́ọ̀rin nínú ìtumọ̀ afọ̀ nípele-ǹ-pele.

## ATỌ́KA AJẸMỌ́TUMỌ̀ ONÍDÈ ÀLÒPỌ̀ ÌṢEWẸ́KÚ NÍNÚ AFỌ̀

Púpọ̀ àwọn àtúnpín ìsọ̀rí ọ̀rọ̀-orúkọ Yorùbá ló ní àdámọ́ atọ́ka ìṣẹ̀nbáyé tó ń mú ìṣewẹ́kú bá ìlò irú ọ̀rọ̀- orúkọ bẹ́ẹ̀ ní àlòpọ̀ pẹ̀lú ọ̀rọ̀-ìṣe. Bí àpẹẹrẹ, ìṣàpèjúwe ìṣewẹ́kú ọ̀rọ̀-ìṣe àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ wọ̀nyí ni a lè tọ́kasí nípò dídára àti nípò ìdíbàjẹ́ báyìí

| S/N | Ọ̀rọ̀-orúkọ | Atọ́ka ọ̀rọ̀-ìṣe nípò dídára | Atọ́ka ọ̀rọ̀-ìṣe nípò ìdíbàjẹ́ |
|---|---|---|---|
| (i) | Ẹ̀kọ (ṣíṣù) | le (lọ́wọ́) | pinyìnkìn / rọ̀ |
| (ii) | Ẹyin (ẹ̀yẹ abìyẹ́) | dára | bu (òbu ẹyin) |
| (iii) | Ọbẹ̀ | dùn | kan |
| (iv) | Ògì | kan | ta (ní ìdin) |
| (v) | Ilá | rọ̀ (lẹ́nu ọbẹ̀) | kó |
| (vi) | Eyín | funfun | dípẹ̀tà |

Àkíyésí wa ni pé, kí ìṣewẹ́kú àlòpọ̀ àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ wọ̀nyí tó lè wáyé, àmúlò atọ́ka ọ̀rọ̀-ìṣe ajẹmáṣà gbọdọ̀ jẹ́ mímú lò. Bí àpẹẹrẹ, ìṣàpèjúwe ajẹmáṣà ẹ̀kọ tó wà nípò ìdíbàjẹ́ ni 'pinyìnkìn'. Bí a bá ṣe ìfiró̩pò èyí pẹ̀lú 'bàjẹ́', kò ní ìtumọ̀ kíkún bíi ká lò ó pẹ̀lú ọ̀rọ̀-ìṣe àdámọ́ ìṣẹ̀nbáyé. Bákan náà, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé, aṣafọ̀ le wí pé ẹyin adìẹ 'ti bàjẹ́' dípò 'di òbu', tàbí kó wí pé ògì-ẹ̀kọ mímu tàbí ṣíṣàn 'dùn' dípò pé 'ó kan', yíyípadà ìtumọ̀ hàn gedegbe. Bí a bá ṣàmúlò atọ́ka àlòpọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe tó ní ìṣewẹ́kú fún ọ̀rọ̀-orúkọ, ìtumọ̀ ajẹmáṣà (ìṣẹ̀nbáyé) ni yóò jẹ́ àmújáde. Àwọn atọ́ka àlòpọ̀ wọ̀nyí, onídè ni wọ́n nínú afọ̀. Bí àpẹẹrẹ, 'pinyìnkìn' àti 'ẹ̀kọ', kò ṣeé yà nílànà ìṣàpèjúwe ẹ̀kọ tó ti bàjẹ́; bẹ́ẹ̀ ni a kì í sábà lò 'pinyìnkìn' pẹ̀lú ohun mìíràn yàtọ̀ sí ẹ̀kọ-ṣíṣù tó ti bàjẹ́; àyàfi, nínú ìyapa afọ̀ láti fi ète ìṣọwọ́ kan pàtó hàn.

Lọ́nà mìíràn ẹ̀wẹ̀, atọ́ka àlòpọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe pẹ̀lú ọ̀rọ̀-orúkọ ìṣẹ̀nbáyé lè ṣàmúlò ọ̀rọ̀-ìṣe onídè méjì, mẹ́ta tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ nínú afọ̀. Bí àpẹẹrẹ, a lè ṣàpèjúwe ìjẹyọ àlòpọ̀ atọ́ka ọ̀rọ̀-ìṣe tó nísopọ̀ pẹ̀lú ìṣu báyìí:






Onídè ni àlòpọ̀ àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe máràárùn tí a tọ́kasí lókè yìí jẹ́ sí ìṣu; ìdí sì nìyí tí àwọn àlòpọ̀ wọ̀nyí ṣe máa ń jẹyọ nínú afọ̀ ní àlòpọ̀ pẹ̀lú ìṣu. Bí àpẹẹrẹ, wọ́n máa ń jẹyọ nínú ọ̀rọ̀ àkànlò-èdè Yorùbá pé 'bí ìṣu ṣe kú, bí ọ̀bẹ ṣe bẹ́ ẹ́'; tàbí a kì í mọ̀wà ilẹ̀ kó kú ni níṣu'; ó 'gọ̀ ju ìṣu lọ'; àti tí 'ìṣu rọgùn'. Lára ìṣu ni a ti ṣe ìsínípò àkàwé fún ohun àfipè mìíràn nínú afọ̀ mìíràn pé 'ọpọlọ rẹ̀ kò níí jọ̀bà' ìtumọ̀ èyí ni pé 'ìyè rẹ̀ kò ní ra': ọpọlọ rẹ̀ kò níí kú sára bí ìṣu inú ebè. Ẹ̀dà àlòpọ̀ ìṣewẹ́kú ọ̀rọ̀-ìṣe ìṣu ni a ṣe ìsínípò padà fún pẹ̀lú 'ọpọlọ' ní àyè yìí. Lọ́nà mìíràn, a nílò ìmọ̀ kíkún nípa ìtumọ̀ ìṣu tó jọ̀bà; èyí tíí ṣe ìṣu tó ti kú sínú ebè, tí kò le hù mọ́ bí a bá gbì ín; ká tó le ní ìtumọ̀ rẹ̀ nínú afọ̀ ìṣínípò 'ọpọlọ tó jọ̀bà'. Èyí ni ọpọlọ tó ti kú. Nínú afọ̀ àfiwé, a máa ń ṣọ̀díwọ̀n àdínkù fún ìṣu tí a ń sè lọ́wọ́ tí iná kú nídìí rẹ̀ lái tíì jiná, tó 'gọ̀' sórí iná ní ẹ̀dà àlòpọ̀ pẹ̀lú ẹ̀dá-ọmọnìyàn pé 'ó gọ̀ ju ìṣu lọ'. Ìṣu tó gọ̀ sórí iná kò lè jinná mọ́; bẹ́ẹ̀ ni ẹni tó gọ̀ ju ìṣu lọ kò lè ní làákàyè ọmọnìyàn tà bí abẹ̀dá mọ́. Síwájú sí i, 'rọgùn' ni àpólà-ìṣe tí a sábà máa ń lò ní àlòpọ̀ pẹ̀lú ìṣu. Ìdí nìyí tí a fi máa ń pa á lówe pé 'a kì í bá oníṣu wá á débi egùn' (Ṣótúndé 2009, o. i. 116). Ìṣu egùn tàbí egùn ìṣu ni a máa ń fi pèbù. Èyí túmọ̀ sí agbára láti lè ṣe ìfiró̩pò ìṣu yàtọ̀ sí ojúlówó tó mú wáyé. Òngo ìṣu ló máa ń pẹyin láti di egùn. Ẹ̀dà ìtumọ̀ 'rọ egùn' ara ìṣu ni ìtumọ̀ ẹ̀dà ti lè wáyé nínú afọ̀ mìíràn. Bí àpẹẹrẹ, ọmọkùnrin tó ti bàlágà ni a lè ṣàpèjúwe bí ẹni tó ti 'rọ ẹpọ̀n' tàbí 'rọ eyín'. Lọ́nà mìíràn, ìṣu le 'wọ́wé' bí ohun ọ̀gbìn eléwé mìíràn, ìṣu le 'jóná', bí ohun mìíràn tí a lè sè lórí iná. Ìṣu lè 'ta', bí ohun ọ̀gbìn tí ń ta bí ìṣu yòókù. A rí àwọn àlòpọ̀ wọ̀nyí bí èyí tí kò wà ní ìsọ̀rí àlòpọ̀ ìṣewẹ́kú ọ̀rọ̀-ìṣe onídè; nítorí àyè ìjẹyọ àlòpọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe

tàbí àpólà ìṣe wọ̀nyí kò dúró lójú kan bí àwọn àpẹẹrẹ márùn-ún tí a tọ́ka sí ṣáájú.

Ọ̀nà mìíràn tí atọ́ka àlọ̀pọ̀ ìṣewẹ́kú ajẹmọ́tumọ̀ onídè tún tí lè jẹyọ ni nínú afọ̀ ajẹmọ́fọ̀; pàápàá, ìṣọ̀rí ọ̀fọ̀ máyẹ̀ tàbí ọ̀fọ̀ bítíírí. Nínú ìhun irú ìṣọ̀rí afọ̀ yìí, a má a ṣàmúlò atọ́ka 'nì í, 'ni' àti 'kì í'. Nínú ìṣọ̀rí afọ̀ yìí, òté àti bátànì ìhun àti ohun àfipè (ìtọ́kasí) jẹ́ ti ìpilẹ̀ tàbí àtayébáyé', kò ṣeé yí padà tàbí ṣe pàṣípààrọ̀ fún rárá; bí èyí bá wáyé, ìṣewẹ́kú ìtumọ̀ afọ̀ yóò yẹ̀bá kúrò ní ọ̀pọ́ àṣà àwùjọ. Bí àpẹẹrẹ,

Ẹni tó bá pagùn kì í kádùn
Ẹni tó bá pàkàlàmọ̀gbò kì í pọ́sù mẹ́fà
Ẹni tó bá pa lekelèké kì í kọ́ṣù mẹ́ta

A lè ṣàpèjúwe ìpèdè (ọ̀fọ̀) yìí pẹ̀lú àlàyé yìí:

Ẹni ——→ pa ——→ Ìgún (– ọdún kan/oṣù méjìlá)
Ẹni ——→ pa ——→ Àkàlàmọ̀gbò (–oṣù mẹ́fà)
Ẹni ——→ pa ——→ Lekelèké (–oṣù mẹ́ta)

OR aṣàfihàn (+ènìyàn) ORIS OROR (EYOR aṣàpèjúwe)

A lè ṣàpèjúwe àbúdá àdámọ̀ ìjọra àwọn ẹyẹ tí a ṣètọ́kasí nínú afọ̀ ọ̀fọ̀ òkè yìí láwọn ọ̀nà wọ̀nyí:

(i) Ẹyẹ abọ̀hun ni àwọn ẹyẹ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta
(ii) Ẹyẹ igbó ni wọ́n (wọn kì í ṣe ohun ọ̀sìn abìyé)
(iii) Ènìyàn (Ẹni) ni wọ́n tọ́ka sí
(iv) Ìpele onídajì ní ìjẹyọléra/ìwàlẹ́ra ìtayọ ìjìyà ìṣèlòdìsí (pípa) àwọn ẹyẹ wọ̀nyí sira wọn. Bí àpẹẹrẹ, Ìgún =oṣù méjìlá, Àkàlàmọ̀gbò = oṣù mẹ́fà àti Lekelèké= oṣù mẹ́ta
(v) Ọ̀rọ̀-ìṣe onídè (pa) ni èèwọ̀ ẹyẹ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta

Onídè ni ìhun (àkoónú èròjà ẹ̀dá-èdè) àti ìtumọ̀ afọ̀ yìí. Ìbí ìjẹyọ tàbí àyè-ìjẹyọ àwọn ọ̀rọ̀-èdè kò ṣeé ṣí nípò rárá. Àbùdá ìṣẹ̀dá abọ̀hun àwọn ẹyẹ wọ̀nyí máa ń mú kí ẹ̀mí wọn gùn. Abálájọ, nínú afọ̀ mìíràn, ó máa ń jẹyọ pé 'Gúnnugún kì í kú léwe, bẹ̀ẹ̀ ni



Àkàlàmọ̀gbò kì í pọdún jẹ'. Lédè mìíràn, 'ẹyẹ tó bá fara wégún, ẹ̀yin ààrò ni yóò sùn'. Ìtọ́kasí àwọn afọ̀ wọ̀nyí ṣàtìléyìn fún ìṣewẹ́kú (onídè) àwọn ohun àfipè inú afọ̀ yìí. Nínú afọ̀ ajẹmọ́fọ̀ mìíràn, àbùdá abọ̀hun àwọn ẹyẹ wọ̀nyí tún jẹyọ. Bí àpẹẹrẹ "ẹbọ kẹ̀bọ kì í pa gún, òkúkòkúù kì í pa Àkàlàmọ̀gbò..." (Fábùnmi 1972, o. i. 40). Èyí fihàn pé, ohun jíjẹ tí a mọ mọ àwọn ẹyẹ wọ̀nyí kò lè ṣokùnfà ikú àìtọ́jọ́ fún wọn pẹ̀lú. Èyí tí a sì máa ń tọ́ka sí nínú afọ̀ ajẹmọ́nídè (ọ̀fọ̀).

## ATỌ́KA AJẸMỌ́TUMỌ̀ ÌFỌ̀NKÁ-AṢÈYÀTỌ̀ ÀLỌ̀PỌ̀ ÌṢEWẸ́KÚ NÍNÚ AFỌ̀

Ọ̀nà mìíràn tí ìjẹyọ ìtumọ̀ lè gbà wáyé nínú afọ̀ ni lọ́nà ìfọ̀nká-aṣèyàtọ̀. Èyí máa ń jẹyọ nígbà tí ohun tàbí àwọn ohun ìtọ́kasí (àfipè) bá yàtọ̀ sira wọn; bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àmújáde ìtumọ̀ kan náà ni ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ohun àfipè náà ń tọ́kasí. Èyí lè jẹyọ nínú afọ̀ ajẹmọ́wé. Bí àpẹẹrẹ,

(i) Olóńgìnní/Músù ←——→ Ológbò
(ii) Ewú ←——→ Òkété
(iii) Ewújù ←——→ Ọ̀yà
(iv) Ẹtà ←——→ Músù-igbó
(v) Ìtú ←——→ Obúkọ
(vi) Ahun ←——→ Ìjàpá
(vii) Erè ←——→ Ẹjọ̀lá
(viii) Ìgalà ←——→ Àgbọ̀nrín

Ohun àfipè (ìtọ́kasí) kan náà ni àwọn orúkọ méjèèjì tí a fi àmì igi oníbùú-olórí-ọfà ṣàpèjúwe nínú àwọn àpẹẹrẹ òkè wọ̀nyí; ṣùgbọ́n ìjẹyọ wọn máa ń ní ìṣewẹ́kú àlọ̀pọ̀ nínú afọ̀. Bí àpẹẹrẹ, 'Olóńgìnní tàjò dé, èkúté-ilé para mọ́'. Èyí wọ́pọ̀ nínú ìlànà ìṣafọ̀ ju 'Olóńgbò tàjò dé, èkúté-ilé para mọ́' lọ. Lọ́nà mìíràn, 'Olóńgbò tí yóò pàkéré, ojú rẹ̀ á wọmi (Ọláoyè 2012, o. i. 55) wọ́pọ̀ ju àmúlò àfipè 'Olóńgìnní' lọ. Nínú afọ̀ mìíràn, ìjẹyọ 'Òkété' ni a máa ń lò dípò 'Ewú' nínú afọ̀ bí i 'Òkété tí dọ́jà tán kò tó káwọ̀ lérí' (Ṣótúndé 2009, o. i. 292). Lọ́nà mìíràn, 'Ewú' ni a ń ṣàmúlò dípò 'Òkété' nínú afọ̀ bí i 'a kì í rí ewú lóde ọ̀sán'. Nínú afọ̀ ọ̀fọ̀ àwúre,

ìjẹyọ àlọ̀pọ̀ tí a máa ń ṣàbà lò ni 'Ẹtà níí kọ́kọ́ tà láàrin ẹranko', a kì í gbọ́ 'Músù-igbó ni í kọ́kọ́ tà láàrin ẹranko'; bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ohun àfipè kan náà ni 'Ẹtà' àti 'Músù-igbo'.

Ìtumọ̀ afọ̀ onítumọ̀ ìfọ̀nká-aṣẹ̀yàtọ̀ tún le wáyé pẹ̀lú ọ̀rọ̀-orúkọ ajẹméranko. Bí àpẹẹrẹ,

ÈKÚTÉ →
- Aṣínrín (òórùn/ẹnu ṣọ́nṣọ́)
- Àfè
- Àgọ̀ọ́ (ọgbọ́n)
- Olósè
- Mọ̀láàjú (ara gúọgùọ)
- Olórògbóò/Ọ̀fọ́n-ọ̀n/Ajẹ-lójú-oníle
- Èkúté-ilé
- Líìlí (onírun-abìpẹ́)
- Ẹdá
- Ẹgbárá (ẹwá)
- Ẹmọ́
- Èlírí (kíkéré)

Ọ̀kọ̀ọ̀kan ẹ̀yà èkúté wọ̀nyí ni a lè rí ìjẹyọ wọn nínú afọ̀ onítumọ̀ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ tí kò lè jẹyọ papọ̀. Bí àpẹẹrẹ, nínú afọ̀ ajẹmọ́wé, a máa ń ṣafọ̀ pẹ̀lú ẹ̀yà àwọn èkúté pé: 'Aṣínrín lóhùn kọ̀wọ̀sí, ó fẹnu rẹ̀ gbẹ́ pẹ́nsùlù', Àgọ̀ó tó gbọ́n ṣáṣá, èbìtì pa á, ambèlètàsé Mọ̀láàjú abara gúọgùọ.' Olóńgìní tàjò dé, èkúté ilé paramọ́'. A tún lè rí i bí ìkìlọ̀ pé 'A kì í ṣòòṣà lójú Ọ̀fọ́n-ọ̀n.' 'Ajá tí ó pa Líìlí, ẹnu rẹ̀ yó ṣẹ̀jẹ̀'. 'Ẹmọ́ kú ojú òpó dí'. Bẹ́ẹ̀ ni a sì lè rí ìlò ẹ̀yà èkúté 'ẹdá' nínú afọ̀ àfiwé pé 'pamọ jọ bí ẹdá'. Àbùdá àdámọ̀ ìbísí ni a mọ̀ mọ ẹ̀yà èkúté yìí; yàtọ̀ sí àwọn ẹ̀yà èkúté yòókù. Nínú afọ̀ mìíràn, a lè ní 'ọ̀dádá tíí jékù ẹdá'; bẹ́ẹ̀ ni a ń lo èlírí pé 'èèpo ẹ̀pà jọ pósí èlírí'. Ẹwà ni à ń lò pẹ̀lú 'ẹgbárá', nínú afọ̀ àfiwé pé 'dára bí ẹgbárá'' Inú oko tó bá mọ́, tí igbó kò pọ̀ níbẹ̀ ló sábà máa ń gbé. Ọ̀kọ̀ọ̀kan ibi ìjẹyọ àwọn afọ̀ wọ̀nyí ló fi ìyàtọ̀ hàn, ṣé jíjọ ló máa ń jọ, Òṣùpá ò le dà bí Òòrùn. Ọ̀kọ̀ọ̀kan ẹ̀yà èkúté wọ̀nyí yàtọ̀ síra wọn ní iṣẹ̀dá, ìrísí àti ní ìhùwàsí; ṣùgbọ́n, èkúté ni àfipè tí ó so gbogbo wọn papọ̀.



Ọ̀nà mìíràn tí ìjẹyọ atọ́ka ajẹmọ́tumọ̀ ìfọ̀nká-aṣẹ̀yàtọ̀ àlọ̀pọ̀ ìṣẹ̀wẹ̀kú lè gbà wáyé nínú afọ̀ ni a júwe pẹ̀lú afọ̀ yìí:

Ẹni tó bá mọ Agbe kó ṣèdárò aró/Agbe ń relé ìdáró

Ẹni tó bá mọ Àlùkò kó ṣèdárò Osùn/Àlùkò ń relé ìkosùn

Ẹni tó bá mọ Lékelèké kó ṣèdárò ẹfun/Lékelèké ń relé ìkẹ́fun

Ẹni → mọ → Agbe = Aró
Ẹni → mọ → Àlùkò = Osùn
Ẹni → mọ → Lékelèké = Ẹfun

ORÓR (Ènìyàn) ORIS ORÓR ORÓR (Aṣẹ̀yàn)

A lè ṣàgbékalẹ̀ àbùdá àdámọ̀ fún ìdámọ̀ ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn èròjà inú afọ̀ òkè yìí báyìí:

(i) Ìtọ́kasí àbùdá (ọmọnìyàn) ni gbólóhùn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta: 'ẹni'
(ii) Àmúlò ọ̀rọ̀-ìṣe kan náà ní gbólóhùn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta ṣàmúlò: 'mọ̀'
(iii) Ẹyẹ inú-igbó ni gbólóhùn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta tọ́ka sí, pẹ̀lú ẹ̀yà ọ̀tọ̀
(iv) Àmì ìsopọ̀ ìtọ́kasí ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn yàtọ̀ gbedegbe: (Agbe → Aró), (Àlùkò → Osùn) àti (Lekelèké → Ẹfun).

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé, àwọn ohun àfipè wọ̀nyí jẹ́ ẹyẹ, ìtọ́kasí ibi ìjẹyọ wọn yàtọ̀; èyí tó mú kí ìṣẹ̀yàtọ̀ wáyé láàrin ìtumọ̀ gbólóhùn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta.

Afọ̀ onítumọ̀ ìfọ̀nká-aṣẹ̀yàtọ̀ tún lè jẹyọ nípasẹ̀ ọ̀rọ̀-orúkọ ajẹmọ́-ohun-aláìlẹ́mìí; nínú èyí tí ìjẹyọ onírúurú ohun kan náà yóò ti wáyé. Bí àpẹẹrẹ, 'omi' le jẹyọ láwọn ọ̀nà ìṣàpèjúwe wọ̀nyí:




Nínú orísìí afọ̀ Yorùbá ni ọ̀kọ̀ọ̀kan ìjẹyọ 'omi' ti le wáyé láti fún wa ní ìtumọ̀ ìṣewẹ́kú àlọ̀pọ̀ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀; bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àlọ̀pọ̀ ìṣewẹ́kú ìtumọ̀ lè wáyé pẹ̀lú àbùdá ohun tó so wọ́n papọ̀: 'omi'. Bí àpẹẹrẹ, nínú afọ̀ ajẹmọ́fọ̀ ni a ti rí afọ̀ ìsàlẹ̀ yìí:

Àbùdí ni **tomi**

Àbùdí ni **todò**

A kì í **bu odò** kó lójú

A kì í bu **ọ̀sà** kó lámì (Fábùnmi 1972, o. i. 29)

'Omi', nínú afọ̀ òkè yìí fọ́ńká fún wa ní orísìí ìtọ́kasí omi méjì: 'odò' àti 'ọ̀sà'. Àlọ̀pọ̀ yìí tún lè jẹyọ nínú afọ̀ mìíràn pé: 'a kì í rídìí òkun, a kì í rídìí ọ̀sà'; èyí tó fi ìjẹyọ àbùdá àwòmọ́ (jíjìn) hàn. Èyí mú kí ìtumọ̀ wọn wáyé láyè ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ sí ìsọ̀rí àwọn omi yòókù tí wọn kò pín nínú àbùdá jíjìn. Nínú afọ̀ àkànlò-èdè, àbùdá àdámọ́ yìí máa ń jẹyọ ní àwòmọ́ pẹ̀lú ìgbé-ayé ẹ̀dá. Bí àpẹẹrẹ, 'ayé **lòkun**,



ènìyàn **lọ̀sà'**. Èyí fi agbára ìsọ̀rí omi méjèèjì yìí hàn ní àwòmọ́ pẹ̀lú ìgbé-ayé ọmọnìyàn.

Síwájú sí i, ọ̀kọ̀ọ̀kan ìtọ́kasí ló lè jẹyọ nínú ìsọ̀rí afọ̀ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ pẹ̀lú ìtumọ̀ ọ̀tọ̀; èyí tó ń mú kí ìṣàpèjúwe wọn wà ní ìfọ́ńká aṣèyàtọ̀ ìtumọ̀. Bí àpẹẹrẹ:

**Omi òjò**: (i) òjò kò ì dá, a ní kò tó tàná (òwe)

(ii) òjò òru ò pẹni rere (òwe)

(iii) ọjọ́ kan òjò borí ẹgbàá ọdá (òwe)

**Omi odò**: (i) odò kì í gùn lái lórísun (òwe/ọfọ̀)

(ii) a ṣẹ̀ṣẹ̀ tẹṣẹ kan bodò, Ọ̀nì ń fà á (òwe)

**Omi àgbàrá** (i) àgbàrá ò lọ́wọ́ lẹ́sẹ̀ tó fi ń gbé ni lọ (òwe/ọfọ̀)

(ii) àgbàrá òjò ò lóun ò nílé í wó, onílé í ni ò níí gbà fú un (òwe)

**Omi ọ̀sà** (i) ọ̀sà lolórí odò (ọfọ̀)

(ii) Àlùkò ní gbére pàdé Ọlọ́sà (ọfọ̀)

(iii) a kì í rídìí Ọ̀sà (ọfọ̀)

**Omi òkun** (i) Agbe ni í gbére pàdé Olókun (ọfọ̀)

(ii) a kì í rídìí Òkun (ọfọ̀)

(iii) Òkun ti lómi tẹ́lẹ̀ kí òjò tóó rọ̀ sí i.

Ibi ìjẹyọ ọ̀kọ̀ọ̀kan ló ní àlọ̀pọ̀ ìṣewẹ́kú ìtumọ̀, bẹ́ẹ̀ ni méjì tàbí mẹ́ta mìíràn lè jẹyọ nípele ìtumọ̀ aṣèyàtọ̀. Bí àpẹẹrẹ, àlọ̀pọ̀ ìjẹyọ ìṣewẹ́kú máa ń wáyé láàrin 'òkun' àti 'ọ̀sà' bí wọn kì í tilẹ̀ ṣe irú-kaùn-gbé-e-tán. 'Agbe ni í gbé're k'Olókun; Àlùkò ṇ ií gbé're k'Ọlọ́sà' (Fábùnmi 1972, o. i. 10). Bí ẹ̀yà 'omi òkun' ti yàtọ̀ sí ti 'omi ọ̀sà'; bẹ́ẹ̀ ni, àlọ̀pọ̀ atọ́ka ìṣewẹ́kú wọn yàtọ̀ pẹ̀lú: Agbe Olókun, Àlùkò Ọlọ́sà.

## ATỌ́KA AJẸMỌ́TUMỌ̀ ÌFỌ̀NKÁ-ALÁÌṢEYÀTỌ̀ ÀLÒPỌ̀ ÌṢEWẸ́KÚ NÍNÚ AFỌ̀

Ọ̀nà pàtàkì mìíràn tí a lè gbà ṣàfihàn ìṣàpèjúwe ajẹmọ́tumọ̀ afọ̀ ní nípa ìjẹyọ ìfọ̀nká aláìṣèyàtọ̀. Èyí máa ń jẹyọ nígbà tí ohun ìtọ́kasí (àfipè) kan náà bá jẹyọ pọ̀ nínú afọ̀ láì mú ìyàtọ̀ kan kan bá ìtumọ̀. A lè tọ́kasí irúfẹ́ ìjẹyọ ìtumọ̀ ìfọ̀nká-aláìṣèyàtọ̀ nínú oríṣìí afọ̀ Yorùbá. Ọ̀kan lára ìjẹyọ ìtumọ̀ yìí máa ń wáyé nínú afọ̀ ajẹmọ́we. Bí àpẹẹrẹ:

(i) **Àjànàkú** kò ní èèkàn, ọba tí yóò m'**Érin** so kò tí ì jẹ (Ọláoyè 2010, o. i. 35)
(ii) Ọ̀kú **àjànàkú** là á yàdá sí, Ta ní jẹ́ yagada lójú **erin**? (Ṣótúndé 2009, o. i.35)
(iii) **Àjànàkú** kọjá mo rí nǹkan fìrí, bí a bá r'**Érin** ká pé a r'**Érin** (Ṣótúndé 2009, o. i. 113 & Ọláoyè 2010, o. i. 35)
(iv) **Erín** wó, erin lọ, **Àjànàkú** sùn bí òkè.
(v) **Àjànàkú** tí a gbé ọ̀fin sílẹ̀ dè, **erin** mọjú **erin** kò bá ibẹ̀ lọ (Badà 1970, o. i. 4 & Ṣótúndé 2009, o. i. 13)
(vi) Ọdọọdún ni **ilá** í so ogún; ọdọọdún ni **Ìrókò** í so ọgbọ̀n (Fábùnmi 1972, o. i. 5)

Nínú àwọn àpẹẹrẹ àkọ́kọ́ dé ìkarùn-ún (i-v), ohun ìtọ́kasí (àfipè) kan náà ni 'Erin' àti 'Àjànàkú' nínú afọ̀ ajẹmọ́we wọ̀nyí. Ohun kan náà ni a ń tọ́kasí láì sí ìyàtọ̀ rárá. Nínú àpẹẹrẹ kẹfà (vi) ẹ̀wẹ̀, ọ̀kan náà ni àmúјáde gbólóhùn afọ̀ ajẹmọ́fọ̀ náà. Ẹyà ilá ni Ìrókò: ilá Ìròkò. Lọ́nà mìíràn, ìtumọ̀ láti ara ọ̀rọ̀-orúkọ lè ṣokùnfà ìjẹyọ afọ̀ àlòpọ̀ ìṣewẹ́kú onítumọ̀ ìfọ̀nká-aláìṣèyàtọ̀. Bí àpẹẹrẹ: **'Asírin kú, Ẹtà rù Ú, Ìkamùdù** ń kọ́fẹ' Àbùdá àjọpín àwọn ohun ìtọ́kasí (àfipè) inú afọ̀ yìí ni: òórùn; èyí tí a tún lè ṣàkàwé báyìí:



ÒÓRÙN → Asínrín (kú)
ÒÓRÙN → Ẹtà rù Ú (Ú: Asínrín)
ÒÓRÙN → Ìkamùdù ń kọ́fẹ (ké 'ọfẹ' kí ẹ̀rù má pa ẹni tó rù ú)

Asínrín jẹ́ èkúté olóòórùn, ẹtà jẹ́ ẹranko abìwo olóòórùn; bẹ́ẹ̀ sì ni ìkamùdù jẹ́ kòkòrò olóòórùn. Àbùdá ìtumọ̀ òórùn ni a ṣàmúlò lára àwọn ohun ìtọ́kasí wọ̀nyí láti mú ìtumọ̀ kan náà jáde; èyí ni pé: èwo lèwo?; ọ̀kan-ò-gbékan bí òwú fìtílà àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ohun ìtọ́kasí mẹ́ta ni afọ̀ yìí ṣàmúlò, síbẹ̀, kò sí ìyàtọ̀ lára àwọn àbùdá ìtọ́kasí: òórùn tí ìtumọ̀ kọ̀ọ̀kan mú jáde. Ẹṣin àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ̀ inú òwe ni wọ́n

Ẹ̀wẹ̀, ìjẹyọ afọ̀ onítumọ̀ ìfọ̀nká-aláìṣèyàtọ̀ ni a lè tọ́kasí nínú afọ̀ ajẹmọ́ríkì. Bí àpẹẹrẹ, Fábùnmi (1972, o. i. 71) ṣàgbékalẹ̀ oríkì ejò báyìí:

Akáwéréké-má-ṣẹ̀ẹ́; Anàgbàlàjà-má-kákò; ọjá f'orí-pitú; ọjá-olórí-Ìgbàmì-wáìyé; Afàìyà falẹ̀; Ìpẹ́pẹ̀-orí-imọ̀-f'ẹnu-ṣ'ẹ̀gún lorúkọ a á pe ìwọ ejò: Aṣábìrù-párá; Aṣábìrù-gànte; Arìngànná- gànná gun-'gànná; Ajágbó-jẹ-wọ́nyín-wọ́nyìn:ọ̀jò-ṣú-rọ̀dọ̀rọ̀dọ̀ -má-rọ̀;ó-'ojú-wẹnkẹ-wẹnkẹ; **Ìwọ ejò náà ni i jẹ́ bẹ́ẹ̀.**

Oríkì-orúkọ ìtọ́kasí àlòpọ̀ ìṣewẹ́kú méjìlá ni afọ̀ òkè yìí ṣàmúlò láti tọ́kasí ejò. Ejò náà ló ni oríkì-orúkọ méjèèjìlá àti orúkọ wọ̀nyí. Èyí fihàn pé, ìṣàpèjúwe ìfọ̀nká- aláìṣèyàtọ̀ àlòpọ̀ ìṣewẹ́kú ni afọ̀ ajẹmọ́ríkì sábà máa ń jẹ́. Barber (1991, o. i. 71) wòye pé, orúkọ ló máa ń dúró bí oríkì. Ọlátúnjí (1984/2005, o. i. 89) ní àṣọdorúkọ máa ń kún inú oríkì; èyí tó máa ń ní oríṣiríṣi ìrísí; ṣùgbọ́n, èyí tó wọ́pọ̀ jù lọ ni àfòmọ́-ìbẹ̀rẹ̀ àti awẹ́-gbólóhùn, àfòmọ́-ìbẹ̀rẹ̀ àti ọ̀rọ̀-orúkọ. Ìrísí ìsọdorúkọ yìí sábà máa ń ní àfòmọ́ ìbẹ̀rẹ̀ 'a' àti awẹ́-orúkọ. Ìrísí ìsọdorúkọ yìí sábà máa ń ní àfòmọ́ ìbẹ̀rẹ̀ 'a' àti awẹ́-gbólóhùn àti 'ò' tàbí 'ọ' àti awẹ́-gbólóhùn; nígbà tí àwọn tó ní ìhun àfòmọ́-ìbẹ̀rẹ̀ àti ọ̀rọ̀-orúkọ sábà máa ń jẹ́ 'àbí' àti ọ̀rọ̀-orúkọ. Àpẹẹrẹ ìhun ìsọdorúkọ àti awẹ́-gbólóhùn nílànà ìhun tí afọ̀ ajẹmọ́ríkì òkè yìí tẹ̀lé.

## ATỌ̀KA AFỌ̀ AJẸMỌ́TUMỌ̀ ÌFỌ̀NKÁ-AṢÈYÀTỌ̀ ONÍBÀÁTAN ÌṢEWẸ́KÚ ÀLÒPỌ̀

Ìtumọ̀ ìfọ̀nká-aṣèyàtọ̀ tún lè jẹyọ lọ́nà ìbátan. Èyí máa ń jẹ́ ìjẹyọ ohun àfipè ìtọ́kasí ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ tí wọ́n tan lọ́nà kan tàbí ní ọ̀na òmíràn. Àjọṣepọ̀ ìbátan yìí máa ń jẹyọ nínú afọ̀ Yorùbá. Bí àpẹẹrẹ, 'bí a bá ń bú **ẹtù**, orí a sì máa fọ́ **awó**; tàbí, bí a bá ń yin **ẹtù**, orí **awó** a sì máa wú (Fábùnmi 1972, o. i. 7) 'Ẹtù' àti 'awó' jẹ́ ẹyẹ-ọ̀sìn abìyẹ́ tí wọ́n jọra. Ìyàtọ̀ láàrin wọn ni pé, 'ẹtù' a máa tóbi ju 'awó' lọ. Funfun ni àwọ̀ 'awó' máa ń jẹ́, tí 'ẹtù' sì máa ń ní àwọ̀ kàlá-ń-kìn-ní lára. Nínú afọ̀ àjọṣepọ̀ mìíràn, Yorùbá á ní 'àgbà lẹtù, ọmọdé lawó''. Èyí ṣàfihàn ìyàtọ̀ ìbátan láàrin 'ẹtù' àti 'awó'. Bí adìẹ funfun ti jẹ́ àgbà adìẹ, bẹ́ẹ̀ ni 'ẹtù' jẹ́ àgbà fún 'awó'. Irúfẹ́ ìsọ̀rí afọ̀ onítumọ̀ ìfọ̀nká- aṣèyàtọ̀ oníbàátan yìí ni a tún lè rí nínú afọ̀ ajẹmọ́we pé 'ìbátan àlábahun kò ju mẹ́ta lọ: **Iyánníbo, Ìrère** àti **Ahun** fúnra rẹ̀. Ìpò ìtumọ̀ ìfọ̀nká-aṣèyàtọ̀ oníbàátan ni òwe yìí wà. 'Iyánníbo' jẹ́ ìyàwó alábahun; ìdí nìyí tó fi máa ń jẹyọ, pàápàá, nínú afọ̀ ajẹmálọ̀ọ́ pé 'Ìjàpá-tìrókò, ọkọ Yánníbo'. Ipò àjọṣepọ̀ tọkọ-taya ni wọ́n wà sí ra wọn nípò ìbátan. Ìrère jẹ́ ẹ̀yà alábahun. Ohun tó ya Ìrère sọ́tọ̀ sí ahun ni pé, ọrùn Ìrère gùn ju ọrùn Ahun (Ìjàpá) lọ. Síwájú sí i, igbá ẹ̀yìn Ìrère a máa lẹ́wà àdámọ́ ju ti alábahun lọ. Ahun (Ìjàpá) máa ń gbé ibi pàlàpálá òkúta àti ní ilẹ̀ ọ̀dàn; ṣùgbọ́n, Ìrère máa ń gbé ibikíbi títí dénú omi. Ipò ìbátan mìíràn tó farapẹ́ èyí ni èébú 'àlọ ni ti ahun, ti abọ ni ti àna rẹ̀' Ipò ìbátan ẹbí ni afọ̀ yìí tún ṣàtìlẹ́yìn fún. Nínú ìtàn ajẹmọ́we yìí, Badà (1970, o.i. 10) ní olè ni ahun ja àna rẹ̀ tó mú kí wọ́n dè é mọ́ igi ní ẹ̀bá-ọ̀nà. Gbogbo àwọn tó ń kọjá ti wọ́n rí i ní dídè bẹ̀rẹ̀ sí níí sọ pé 'o ò rí ahun àna rẹ̀ ló tún jà lólè'. Nígbà tó ń pẹ́ lóríṣo jù bọ́ṣe yẹ lọ, tí ọ̀pọ̀ òjò àti òòrùn dá mọ́ ọn lórí, àwọn olùrékọjá yí ohùn padà pé 'ọ̀tọ̀tọ̀ èyí làna ìgbín; bí kò bá ṣe àna rẹ̀ ńkọ́, ṣé ìbá yọ ọ́ lójú jẹ ni? A tún le wí pé '**Dàda** kò lè jà, àmọ́ ó ní **àbúrò** tó gbójú' (Ajíbọ́lá 1968, o. i. 11). Ipò ìbátan ẹbí ni 'Dàda' àti 'àbúrò' Dàda wà ní àyè ìjẹyọ yìí. Lọ́nà mìíràn, a tún rí ìlò afọ̀ yìí bí ìtàndòwe pé 'a kì í mọ **ìyá Ọ̀ṣọ́** ju **Ọ̀ṣọ́** lọ' (Badà, 1970, o. i. 5). Ìtàndòwe yìí sọ pé, Ọ̀ṣọ́ jẹ́ ẹrú lọ́dọ̀ Baṣọ̀run Ògúnmọ́lá, lẹ́yìn tí ogun ti kó ìyá Ọ̀ṣọ́ lẹ́rú, lái nírètí 'mo-kò-ó' rẹ̀ mọ́ fún Ọ̀ṣọ́. Nípasẹ̀ ìwà ọmọlúàbí Ọ̀ṣọ́ lọ́dọ̀ Baṣọ̀run Ògúnmọ́lá, lọ́jọ́ kan tí inú rẹ̀ dùn sí Ọ̀ṣọ́ ló ránṣẹ́ pè é kó bèèrè ohun tó bá wù ú tí òun lè ṣe fun un. Ọ̀ṣọ́ pìtàn ayé rẹ̀ fún Baṣọ̀run, pàápàá, nípa ìyá rẹ̀ tógun kó lẹ́rú. Ọ̀ṣọ́ ní inú òun yóò dùn bí ìyá òun bá le jẹ́ wíwárí. Èyí mú Baṣọ̀run pàṣẹ wíwá ìyá Ọ̀ṣọ́ kiri, pẹ̀lú ẹ̀bùn fẹ́ni tó bá rí i. Bóyá, nítorí ẹ̀bùn tí Ògúnmọ́lá kó lé rírí ìyá Ọ̀ṣọ́ ni, ló mú kí ọkan lára àwọn ọmọ ọ̀dọ̀ Ògúnmọ́lá sọ pé òun fojú kan ìyá Ọ̀ṣọ́ ní Ìjẹ̀bú-Òde. Ògúnmọ́lá ni kí wọ́n mú Ọ̀ṣọ́ lọ wo obìnrin ọ̀hún. Nígbà tó rí obìnrin ọ̀hún, ó ní kì í ṣe ìyá òhun. Ẹrú tó rí ìyá yìí ní ìyá rẹ̀ ni. Ọ̀rọ̀ di àríyànjiyàn láàrin wọn dé bi pé wọ́n kó ẹjọ́ yìí lọ sọ́dọ̀ Baṣọ̀run Ògúnmọ́lá. Lẹ́yìn tí wọ́n kó, tí wọ́n rò fún Baṣọ̀run tán, Baṣọ̀run béèrè lọ́wọ́ ẹrú náà pé 'ṣé o wá mọ ìyá Ọ̀ṣọ́ ju Ọ̀ṣọ́ ni? A kì í mọ ìyá Ọ̀ṣọ́ ju Ọ̀ṣọ́ lọ. Láti ìgbà yìí ló ti dòwe jákè-jádò ilẹ̀ Yorùbá. Afọ̀ yìí jẹ́ afọ̀ onítumọ̀ ìbátan-ẹbí: tọmọ-tìyá. Kò sí àmúlò ohun èlò tí ìbátan kò lè ṣàfihàn. Kò pọn dandan kó wáyé nínú afọ̀ tó ṣàmúlò ohun abẹ̀mí nìkan. Lọ́nà mìíràn, ìjẹyọ afọ̀ oníbàátan lè wáyé nínú afọ̀ geere bákan náà. Bí àpẹẹrẹ, a lè ní àwọn afọ̀ ajẹmọ́we oníbàátan pé 'ohun tó bá ti bá **ojú ti bámú**' 'ohun tó ba ti kan **ìṣaasùn**, dandan ni kó kan **ṣíbí**' '**àbàtà** ta kété bí ẹni tí kò bá **odò** tan'. Ipò ìbátan ni 'ojú' àti 'imú', 'ìṣaasùn' àti 'ṣíbi', pẹ̀lú 'àbàtà' àti 'odò' wà nínú àwọn afọ̀ òkè yìí.

Afọ̀ kọ̀ọ̀kan ló ní atọ́ka àlòpọ̀ ìṣewẹ́kú tirẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni àwọn atọ́ka ìṣewẹ́kú wọ̀nyí máa ń níí ṣe pẹ̀lú ohun àwùjọ (ajẹmáṣà). Ìwòye yìí ni Alan àti Fabb (1990, o. i. 137) wò pe:

> Together, these various elements create what is called the texture of a text: its property of visibly holding together as connected entity…Different sorts of text create different types of cohesion and texture. Conversations typically draw heavily on material which is taken as 'given' or 'shared', because it can be retrived from immediately surrounding situation.

Lápapọ̀, àwọn fọ́nrán wọ̀nyí máa ń mú ẹwà bá afọ̀: àwọn èròjà rẹ̀ máa ń ṣiṣẹ́ ìsopọ̀ fún àwọn onírúurú ẹ̀yà afọ̀. Ọ̀kọ̀ọ̀kan afọ̀ ló ní orísìírísìí ìṣewẹ́kú àti ẹwà; àṣọgbà máa ń wáyé pẹ̀lú

àwọn ohun àyíká tí a gbé kalẹ̀ tàbí tó ní ìbápín pẹ̀lú ohun mìíràn.

Lọ́nà mìíràn, a lè rí ìṣewẹ́kú àlòpọ̀ nínú afọ̀ àfiwé bí i '**jọra bí imumu**', '**dúdú** bí i kóró-iṣin' tàbí '**apẹ̀**', '**dùn bí oyin**', '**korò bí ewúro**' tàbí '**korò** ju **iwọ** lọ' àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ìṣewẹ́kú àwọn afọ̀ afiwé wọ̀nyí jẹ́ ajẹmáṣà, tí àlòpọ̀ wọn sì jẹ́ pẹ̀lú àwọn ohun àyíká tí a lè fojúrí lọ́pọ̀ ìgbà; bẹ́ẹ̀ ni ìṣàmúlò àlòpọ̀ ìṣewẹ́kú àwọn afọ̀ wọ̀nyí máa ń fún afọ̀ ní ẹwà àti ẹwù ajẹmọ́-ìṣewẹ́kú ẹ̀yà-afọ̀.

## ÌKÁDÌÍ

Iṣẹ́ ìwádìí yìí fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé púpọ̀ ọ̀rọ̀-orúkọ àti ọ̀rọ̀-iṣe Yorùbá, tí a fún ní ìlò nínú afọ̀; pàápàá afọ̀ ajẹmọ́we, ọfọ̀, àkànlò-èdè àti oríkì-lé-ní-àdámọ̀ ìtumọ̀ ìṣẹ̀nbáyé (àṣà). Àmúlò irú àwọn ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ máa ń wáyé láwọn ọ̀nà ìjẹyọ mìíràn nínú afọ̀ ìtumọ̀ ìfọ̀nká-aṣèyàtọ̀, ìfọ̀ká-aláìṣèyàtọ̀ àti bí afọ̀ onítumọ̀ ìfọ̀nká-aṣèyàtọ̀ oníbàátan. Síwájú sí i, ìtumọ̀ àdámọ̀ ìṣẹ̀nbáyé máa ń kún fún ìtumọ̀ tó ní ìsopọ̀ àti ìṣewẹ́kú; èyí tó ń mú kí ìmọ̀lára, ẹwù àti ẹwà àrà-ọ̀tọ̀ irú afọ̀ bẹ́ẹ̀ ju ìjẹyọ irú ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ nínú ìṣínípò ìtumọ̀ inú afọ̀ mìíràn. Bí àpẹẹrẹ, 'gọ̀' ni a tọpinpin ìtumọ̀ rẹ̀ nínú afọ̀ àfiwé àjùlọ 'gọ̀ ju ìṣu lọ', láti ara ìṣu tí kò lè jinná ní sísè mọ́; èyí ni a ṣe ìṣínípò ìtumọ̀ fún nínú afọ̀ ìṣàpèjúwe àfiwé ìtayọ òdiwọ̀n (àjùlọ). Lọ́pọ̀ ìgbà, 'gọ̀ ju ìṣu lọ' ni à ń lò láti ṣe èyí.

Àwọn aṣagbátẹrù onímọ̀-ìṣọwọ́lò-èdè kan fara mọ́ ìlànà púpọ̀ láti ṣàgbékalẹ̀ èrò afọ̀ kan náà. Nígbà tí àwọn alátakò ìlànà èrò yìí wòye pé ọ̀nà kan gbòógì ni a fi lè ṣàmúlò èrò kan. Geoffery àti Short (1981, o. i. 62) ní ìwòye àwọn onílànà púpọ̀ àti ìlànà kan nípa afọ̀ ni pé:

> There can be different ways of conveying the same content. The monist holds that this is a mistake, and that any alteration of form entails a change of content.

Ọ̀tíṣirísí ọ̀nà ni a lè gbà ṣàgbékalẹ̀ èrò pẹ̀lú àkoónú kan náà. Àwọn onílànà kan gbà pé aṣìṣe lèyí jẹ́, àti pé bí àyípadà bá ti bá ìrísí afọ̀, ìyípadà gbọdọ̀ dé bá àkoónú pẹ̀lú.



Èyí fihàn pé, èrò àwọn onílànà kan nípa afọ̀ ṣàtìlẹ́yìn àmúlò afọ̀ onídè; nígbà tí àwọn onílànà púpọ̀ gbà pé ìfọ̀nká, yálà, aṣèyàtọ̀, aláìṣèyàtọ̀ tàbí oníbàátan lè wáyé pẹ̀lú àkoónú afọ̀ pẹ̀lú ìtumọ̀ kan náà.

## ÀWỌN ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ


Alan, D. & Fabb, N. (1990). *Literary studies in action.* New York: Routledge.

Awóyalé, Y. (1991). Ìfojú ìmọ̀-ẹ̀dá-èdè-ajẹmáfọ̀ ṣe ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ lítíreṣọ̀. nínú C. Ajéwọlé (Olótùú.) *Láderin:* Ìwé àtìgbàdégbà ẹgbẹ́-akẹ́kọ̀ọ́ ìjìnlẹ̀ èdè Yorùbá, Yunifásitì Ìlọrin, Ìlọrin. ọ. i. 3-5&32-36.

Badà, S. (1970). *Òwe Yorùbá àti ìṣẹ̀dálẹ̀ wọn.* Ìbàdàn: Oxford University Press.

Bámgbóṣé, A. (1968). The form of Yorùbá proverbs. Nínú *Odù:* Journal of African studies. Vol. 4., No.1. o. i. 85-100.

Barber, K. (1991). *I could speak until tomorrow.* Edinburgh: Edinburgh University Press.

De Beangrande, R. & Dressler, W. (1981). *Introduction to text-linguistics.* London: Longman.

Fábùnmi, M. A. (1972). *Àyájọ́ ìjìnlẹ̀ ohùn ẹnu Ifẹ̀.* Ìbàdàn: Oníbọn-Òjé Press.

Geoffery, N& Short, M. (1981). *Style in fiction: A linguistic introduction to English fictional prose.* New York: Longman group Limited.

Jakobson, R. (1960). *Shifter, verbal categories and the Russian verb.* Cambridge: Mass Harvard University.

Lawal, A. (1997). Aspects of a Stylistic theory and the implications for practical criticism. Nínú A. Lawal

(Olótùú.) *Stylistics in theory and practice*. Ìlọrin: Paragon Book. o. i. 25-47.

Òkéwándé, O. T. (2014). Àgbéyẹ̀wò ète ìṣewẹ́kú nínú ìwé *Orin Ọdẹ Fún Àṣeyẹ*. Nínú A. Abdussalam, L. Adéyẹmí, H. Adéọ̀ṣun & B. Arókoyọ̀ (Àwọn Olótùú.) *Bringing our cultures home*. Festschrift for Bádé Àjàyí at 70. o. i. 99-113.

Olújinmí, B. (2012). The utilization value of Yorùbá proverbs in enterpreneuship. Nínú A. Adéjùmọ̀ (Olótùú.) *Yorùbá: Journal of the Yorùbá studies association of Nigeria*. Ìbàdàn: Hakolad Prints. Vol. 7., No. 1 o. i. 192-213.

Ọláoyè, J.S. (2012). *The principles and concepts of Yorùbá language and 1,122 Yorùbá proverbs* (second Edition). Ìlọrin: FAMOST PRINT MEDIA.

Ọlátúnjí, O. (1984/85). *Features of Yorùbá oral poetry*. Ìbàdàn: University Press.

Ọmọ́tọ́ṣọ̀ọ́, R.K. (2006). Acontext structure analysis (CSA) of Yorùbá proverbs in discourse. A ph.D Thesis submitted to the Department of Linguistics and Nigerian Languages, University of Ìlọrin, Ilọrin.

Ṣótúndé, F. I. (2009). *Yorùbá proverbs and philosophy*. Abẹ́òkúta: Damsan Nig. Company.